# IJOLOOTỌ́ JOBU NINU IDANWO NLA

**Jobu 1:1-22; 2:1-10; 13:15; 23:1-17; 27:1-6; 42:1-17**

**ẸKỌ 372 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Odõdi fun Ọlọrun ti iba fi huwa buburu, ati fun Olodumare, ti yio fi ṣe aiṣedede! Nitoripe ẹsan iṣẹ enia ni yio san fun u, yio si mu olukuluku ki o ri gẹgẹ bi ipa-ọ̀na rẹ̀" (Jobu 34:10, 11).**

**I Idanwo Jobu**

1 Ọlọrun gba Satani làye lati fi wahala ati ipọnju dán igbagbọ́ Jobu wò, Jobu 1:1-22

2 Ọna ète ti Satani lò lati fi dán igbagbọ́ Jobu wò jẹ́ eyi ti a gbà laye ninu eto Ọlọrun lati wẹ awọn eniyan mimọ́ mọ́, ati lati mú awọn ilana Ọlọrun ṣẹ, Jobu 2:1-9; Johannu 15:2; Heberu 12:5-13; 5:8; Romu 8:28

3 A dán Jobu wò lati ọwọ́ Satani ki o ba le jọwọ ara rẹ̀ fun ibi nipa idanwo kikoro, Jobu 1:9-11; 2:4; Daniẹli 3:1-18; Matteu 4:1-11; Luku 22:31

**II Awọn Idayafo Jobu**

1 Aya Jobu gbà á niyanju ki o bú Ọlọrun ki o si kú, Jobu 2:9; Numeri 31:16; 2 Kronika 32:15-18

2 Awọn ọrẹ Jobu mẹta sùn ún ni ẹ̀sun pé ẹ̀ṣẹ ti o ṣẹ̀ ti kò si jẹwọ rẹ̀ ni o fa wahala bá a, Jobu 4:7, 8; 8:6; 11:6, 13-16

3 Ipọnju Jobu mu un fara da ẹgàn ati iyọṣuti si awọn aladugbo rẹ̀, Jobu 30:1-15; Orin Dafidi 41:7-9

4 Aisàn Jobu mú irora nla ati wahala bá a, Jobu 30:16-18

5 Idojukọ Satani mú ki o dabi ẹni pe Jobu kò ri oju Ọlọrun, eyi si mú ipọnju nla bá a, Jobu 9:25-33, 23:1-17

**III Igbẹkẹle Jobu ninu Ọlọrun**

1 Jobu di igbagbọ rẹ̀ ninu Ọlọrun mú bi o tilẹ jẹ pe a mu un fara da idanwo nla ti ipọnju ti ara ati ti ọkàn, Jobu 27:1-6; 19:25-27; 13:15; 1:21, 22; 2:10; 23:10

2 Ọlọrun yi igbekun Jobu pada, igbẹyin Jobu si sàn ju iṣaaju rẹ̀ lọ, Jobu 42:8-17; Oniwasu 7:8

## ALAYE

### Apẹẹrẹ Jobu

Awọn eniyan maa n di olokiki tabi ẹni ẹ̀gan nipa iwa rere tabi iwa buburu ti wọn ba hù bi wọn tilẹ kú, orukọ rere tabi buburu ti a pè mọ wọn ki i fi wọn silẹ. Nipa bayii ni a fi n pe Judasi mọ́ iwa ọdalẹ lati igba ti o ti fi Oluwa rẹ̀ Jesu Kristi hàn. Orukọ Jobu ni a si n pè mọ́ iwa suuru. Orukọ rẹ̀ jẹ́ ti ọla ati ijolootọ nitori iwa iṣotitọ ti o hù ninu ipọnju ti o gbona janjan, ti ara ati ti ọkàn.

Jobu jẹ́ ẹni ti o gba Ọlọrun gbọ́, bi o tilẹ jẹ pe a kò mọ pupọ ninu itan iran rẹ̀, sibẹ orukọ rẹ̀ ati akọsilẹ rẹ̀ n tàn ninu Ọrọ Ọlọrun alaaye. Jobu ṣe oloootọ to bẹẹ ti Ọlọrun fi tọka rẹ̀ si Satani gẹgẹ bi apẹẹrẹ ododo. Lati inu idahun Satani si ibeere Ọlọrun nipa Jobu, o fi hàn pe eṣu ni ipilẹ aigbagbọ́ ti o wà ninu ayé ati ẹ̀gan si Ẹsin Igbagbọ́ ati gbogbo ododo rẹ̀.

Satani sọ bẹẹ nipa Jobu, bẹẹ gẹgẹ ni o si n sọ nipa awọn Onigbagbọ́ pe nitori ère ni wọn ṣe n sin Ọlọrun: mú ère naa kuro, tabi pa wọn lara, wọn yoo sẹ́ Ọlọrun. Igba aimoye lati ayebaye ni Eṣu ti gbiyanju lati gbé idanwo yii dide si awọn eniyan Ọlọrun. Ṣugbọn Ọlọrun ti gbé awọn eniyan dide lọkunrin ati lobinrin, awọn ẹni ti, nipa oore-ọfẹ Ọlọrun, ti wọ́n ti sọ ihumọ Satani di asán nipa iduro gangan wọn fun ododo, bi o tilẹ jẹ pe o gbà pupọ ninu wọn ni ẹmi wọn.

Lai si aniani, itan Jobu jẹ́ ẹkọ nlanla fun awọn ti n tọ Ọlọrun lẹyin. Itàn Jobu jẹ́ ẹkọ fun awọn Onigbagbọ́ pe Eṣu ni o n mú ipọnju ati wahala wá ati pe awọn nnkan bẹẹ ki i ṣe alaini idi ati pe wọn jẹ́ ifẹ Ọlọrun fun awọn eniyan Rẹ̀. Ọlọrun ki i ṣe olupilẹṣẹ ẹ̀ṣẹ tabi ibikibi, tabi ohun ti ibi le mú wá gẹgẹ

bi aisàn tabi ikú. Sibẹ awọn irú nnkan bẹẹ wà ninu ayé ati niwọn igba ti awọn Onigbagbọ́ ba wà ninu ayé, wọn yoo pade ibi, wọn yoo si ṣẹgun rẹ̀. Pe a le pade wọn ki a si ṣẹgun wọn nipa oore-ọfẹ Ọlọrun jẹ́ ẹkọ ti a ni lati kọ́ ninu idanwo ati ipọnju Jobu. A fẹrẹ dán an wò de gongo eyi ti ẹdá le fara dà, ṣugbọn ó jẹ́ olooótọ si Ọlọrun laaarin gbogbo rẹ̀.

**Idanwo Ibi**

Ọkan ninu awọn ẹkọ nla ti awọn eniyan Ọlọrun ni lati kọ́ ninu ipọnju Jobu lati ọwọ́ Satani ni pe ọ̀na pupọ ni o ti n gbé ogun dide si ni lẹẹkan ṣoṣo. Paulu wi pe, "Nitori awa kò ṣe alaimọ̀ arekereke rẹ̀" (2 Kọrinti 2:11); diẹ ninu awọn ọ̀na ti o n gbà ni a fi hàn fun wa ninu iriri Jobu.

A ni lati mọ̀ pe idanwo Jobu jẹ́ ogun ninu ati lode. O ni wahala ati irora pupọ ninu ara, o si tun ja ogun pupọ ninu ọkàn rẹ̀ nitori ẹmi rẹ̀. Lati mú ki ipọnju Jobu pọ si i awọn ti o yẹ ki o jẹ́ iranwọ ati itunu fun un ni o jẹ́ alatako rẹ̀. Awọn ti o yẹ ki o gba a niyanju ninu igbagbọ́ rẹ̀ ninu Ọlọrun ni o di alatakò rẹ̀. Iyawo rẹ̀ paapaa gba a ni imọran pe ki o bú Ọlọrun ki o si kú. Bi o ba ṣe pe Jobu ti feti silẹ si iru awọn imọran bẹẹ oun i ba ti sọ ẹmi rẹ̀ nù titi lai.

Siwaju si i, awọn ọrẹ Jobu mẹta sun un lẹsun fun ẹ̀ṣẹ ikọkọ ti kò jẹwọ rẹ̀ ati pe idi rẹ̀ ni eyi ti awọn ipọnju naa fi dé si i. Sibẹ si i Jobu fi ara da ọ̀pọ ifiniṣẹsin ati ẹ̀gan lati ọdọ awọn aladugbo rẹ̀ ati awọn ti wọn jijọ n ṣe òwò pọ̀. Lati inu Iwe Mimọ́ ni a ri kà pé Jobu jẹ́ ẹni ti a gbega laaarin awọn eniyan, wọn a si maa feti silẹ si ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ bi ọlọgbọn eniyan. Ọrọ̀ ti Ọlọrun fi fun Jobu mú ki o ni okiki ati iyi laaarin awọn eniyan. Ṣugbọn nigba ti awọn ọrọ̀ naa parun ti oun paapaa lọ sinu okiti eeru, ka sọ ọ bi ọrọ, gbogbo okiki rẹ̀ lo wọmi. O di ẹni ifiṣẹlẹya laaarin awọn ọmọ keekeekee ati ẹni ẹ̀gan laaarin awọn aladugbo rẹ̀.

Ero gbogbo eniyan ni pe irú ipọnju ti o dé bá Jobu yii ki i ṣe ohun miiran bi kò ṣe idajọ Ọlọrun nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀, nitori naa o di ẹni ẹ̀gan nitori ẹ̀ṣẹ ti wọn kò mọ̀ nipa rẹ̀ ṣugbọn ti wọn rò pé o ti dá.

A fi ẹni ti igbagbọ rẹ̀ duro gangan ninu Ọlọrun nikan ni o le fara da irọlu eṣu gẹgẹ bi eyi ti ọkàn Jobu fara gbá. Ọlọrun ki yoo jẹ ki a dán wa wò ju bi a ti le gbà lọ, Ọlọrun mọ pe Jobu le fara dà (ati pe) yoo jẹri agbára igbala ati igbagbọ́ rẹ̀ ninu Ọlọrun. Eredi idanwo naa ni pe ki Jobu le sọ gbogbo ireti ati igbẹkẹle rẹ̀ ninu Ọlọrun nù, ki o si wà lainireti rara. Ipinnu Satani ni lati mú irú ijiya ti kò ṣe fara dà bẹẹ bá Jobu ki o ma baa le ni ireti ati la idanwo naa já. Oore-ọfẹ Ọlọrun tó fún oniruuru idanwo, ó si tó fún aini Jobu pẹlu. Oore-ọfẹ Ọlọrun kò dá Jobu si kuro ninu ijiya ti idanwo naa mú wá loriṣiriṣi ọ̀na, ṣugbọn o mu un jẹ́ olooótọ si Ọlọrun, o si mu un wá sinu iṣẹgun ti o logo fun Ọlọrun.

**Igbagbọ́ Jobu**

Boya eyi ti o le jù ninu idanwo ti o ba Jobu ni ai le ri Ọlọrun nitosi rẹ̀. A le ṣẹgun idanwo nla pẹlu irọrun bi ọkàn wa ba gbẹkẹle Ọlọrun ni igbagbọ́ pe Oluwa ni o mọ ohun ti o dara jù lọ ati pe yoo mú ohun gbogbo wá si opin gẹgẹ bi ifẹ Rẹ̀. Igba kan wà ti Jobu wi pe, "Si wo! bi emi ba lọ si iha ila-õrun, on kò si nibẹ, ati si iwọ-õrun ni, emi kò si roye rẹ̀: … o fi ara rẹ̀ pamọ niha gusu, ti emi kò le iri i: (Jobu 23:8, 9). Bi o ba ṣe pe mimọ nnkan lara ni, o dabi ẹni pe kò si ireti lọna bayii. Ṣugbọn igbagbọ́ ki i ṣe mimọ nnkan lara. Ninu gbogbo rẹ̀, ohun ti Jobu le sọ ni pe, "Ṣugbọn on mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀, nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura" (Jobu 23:10). Igba meloomeloo ni awọn eniyan Ọlọrun ti ri itura ninu ọ̀rọ yii! Nitori pe Jobu ni igbagbọ́ ti o yeje, oun le mú iduro rẹ̀ pẹlu Ọlọrun, bi o tilẹ̀ jẹ́ pe a gba gbogbo ọrọ̀ rẹ̀ kuro, ti irora si fi ara ṣe ile, ti ọkàn rẹ si poruuru nipa atako buburu lati ọdọ awọn aladugbo ati Satani.

Ijẹwọ igbagbọ́ nla Jobu ninu Ọlọrun ni akoko iṣoro rẹ̀ jẹ diẹ ninu awọn ẹsẹ Bibeli ti o lọla jù lọ. Nipa imisi Ẹmi Mimọ́ nikan ni o le sọ asọtẹlẹ akoko igba ti Jesu yoo wá nigba ifara hàn Rẹ̀. Jobu wi pe, "Ati emi, emi mọ̀ pe Oludande mi mbẹ li ãyè, ati pe on bi Ẹni-ikẹhin ni yio dide soke lori erupẹ ilẹ. Ati lẹhin igba awọ ara mi, ti a ti ke e kuro bi iru eyi, ati laili ẹran ara mi li emi o ri Ọlọrun. Ẹniti emi o ri fun ara mi, ti oju mi o si wò, ki si iṣe ti ẹlomiran; ọkàn mi si dáku ni inu mi" (Jobu 19:25-27). Ireti Ajinde ni ireti Ijọ, Jobu si fi ara rẹ̀ hàn bi ẹni ti o yẹ fun Ajinde Ekinni.

Ọrọ Jobu "Bi o tilẹ pa mi, sibẹ emi o ma gbẹkẹle e" wà ni dọgbandọgba pẹlu igbagbọ́ ati igbẹkẹle ti Abrahamu ni nigba ti o fẹ fi ọmọ rẹ̀ rú ẹbọ sisun, ti o sọ bayii pe "Ọmọ mi, Ọlọrun tikalarẹ̀ ni yio pèse ọdọ-agutan fun ẹbọ sisun" (Gẹnẹsisi 22:8).

**Igbẹyin Jobu**

Nikẹyin, Ọlọrun yi ipọnju Jobu pada, O si san ilọpo meji ohun ti a ti gbà lọwọ rẹ̀ pada fun un. Okiki rẹ̀ si kàn rekọja ju bi o ti ri ni iṣaaju. Ọlọrun kò fun un ni ọ̀pọlọpọ ibukun ayé nikan nitori ijolootọ rẹ̀ ṣugbọn ẹri rẹ̀ yoo mú ọ̀pọlọpọ erè ayeraye wá nitori akọsilẹ rere ti o fi silẹ fun Ijọ Ọlọrun.

## AWỌN IBEERE

1. Ẹsun wo ni Satani fi Jobu sun si ni iṣaaju?
2. Ẹsun wo ni o fi sun si lẹẹkeji?
3. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi fi àye silẹ fun Eṣu lati pa Jobu lara?
4. Ki ni iyawo Jobu gbà á ni imọran ki o ṣe?
5. Ki ni awọn ọrẹ Jobu mẹta fi i sun si?
6. Bawo ni a ṣe mọ̀ pé atako Satani le wá ni ilọpo-ilọpo?
7. Sọ diẹ ninu awọn irẹwẹsi Jobu.
8. Ki ni ṣe ti awọn ọrẹ Jobu fi rò pe ó ti dẹṣẹ?
9. Bawo ni a ṣe mọ̀ pé Jobu ni igbagbọ́ ninu Ajinde?
10. Sọ ohun ti Jobu wi lati fi igbagbọ́ rẹ̀ ninu Ọlọrun hàn